**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÀWỌN GBÓLÓHÙN WÒLÎÌ ỌGBỌ̀N**

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 138:8:** Olúwa yóò ṣe ohun tí íṣe ti èmi lí àṣepé: Olúwa, ànú Rẹ dúró láíláí, máṣe kọ iṣẹ́ ọwọ́ ara Rẹ sílẹ̀.

## SỌ ỌKỌ̀Ọ̀KAN ÀWỌN ÌJẸ́WỌ́ WỌ̀NYÍ NÍ ÌGBÀ MÉJE TÍ Ó LỌ S'ÓKÈ

1. A kòní rí ẹ̀jẹ̀ mi lórí pẹpẹ búburú ìyówù, ní orúkọ Jésù.
2. Ikọ̀ ẹgbẹ́ ogun Ọlọ́run yóò lọ sí ilékílé tí mo ti gbé é rí, wọn yóò gba ọrọ̀ mi padà fún mi, ní orúkọ Jésù.
3. Ògo mi t'ó wà ní àtìmọ́lé ìtìjú àti ìdárungún yóò dìde, gba ìtúsílẹ̀, yóò sì fò jáde lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Mo pàṣẹ wí pé gbogbo àlúfà sátání, tí àwọn ọ̀tá mi n san owó oṣù fún yóò gba idà ikú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára tó n bù mí ṣán ní ìkọ̀kọ̀, àrá Ọlọ́run yóò tú àṣírí rẹ lónìí, yóò sì sán an pa ọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Iná ìyípadà atòkèwá yóò ṣekú pa gbogbo ìdárungún nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ọ̀tá ìkà, tó n fọ́nnu lòdì sí mi yóò gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
8. Àwọn agbára tí wọ́n n jà fitafita láti dámipadà sí ẹṣẹ̀-àárọ̀, yóò gba òkúta ìparun, ní orúkọ Jésù.
9. Àwọn agbára tí wọ́n kórira láti gbọ́ ìròyìn rere nípa mi yóò kú ikú tíkòwọ́pọ̀, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo ìdótì àjẹ́ lórí orí mi yóò túká, ní orúkọ Jésù.

11. Gbogbo ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ àbáláyé tí ó ti dèmímọ́lẹ̀, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, fọ́ báyìí, ní orúkọ Jésù.
12. Àwọn tí ó fimí rẹ́rìn tẹ́lẹ̀ rí yóò padà láti bámi rẹ́rìn, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo agbára tí wọ́n ti mu u gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí wọ́n gbà lẹ́kùnrẹ́rẹ́ láti dúkokò mọ́ èmi tàbí àwọn ọmọ mi yóò túká sí ìdahoro, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo akitiyan àwọn ọ̀tá mi yóò kángun sí ìkùnà olóró fún wọn, ní orúkọ Jésù.
15. Ibi gíga ohun ìyówù, tó n bámi rìn nínú ìrìn àjò mi, tó n dá wàhálà sílẹ̀ fún mi, yóò fọ́ sí wẹ́wẹ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
16. Mo sọtẹ́lẹ̀ wí pé gbogbo ọfà ìjàmbá àti ibànújẹ́ kì yóò bà mí, ní orúkọ Jésù.
17. Mo sọtẹ́lẹ̀ sórí ayé mi wí pé látòní lọ, agbárakágbára tó n wa ọ̀fìn fún mi yóò ṣubú sínú ọ̀fìn náà, ní orúkọ Jésù.
18. Mo sọtẹ́lẹ̀ wí pé látòní lọ, gbogbo agbára ìkùnà ní bèbè àlàjá yóò di gbígbé sin in, ní orúkọ Jésù.
19. Mo sọtẹ́lẹ̀ wí pé àwọn tó kórajọpọ̀ láti pẹ̀gàn mi, àjọyọ̀ mi yóò ṣe ojú wọn, ní orúkọ Jésù.
20. Mo sọtẹ́lẹ̀ sórí ayé mi wí pé, èmi yóò tàṣé àwọn ènìyàn tíkò tọ́ ọ́, èmi yóò sì bá àwọn ènìyàn tí ó tọ́ ọ́ pàdé, ní orúkọ Jésù.
21. Mo sọtẹ́lẹ̀ sórí ayé mi wí pé, iṣẹ́-ìyanu tí yóò polongo agbára Ọlọ́run nínú ayé mi yóò ṣẹlẹ̀ lónìí, ní orúkọ Jésù.
22. Mo sọtẹ́lẹ̀ wí pé ẹ̀jẹ̀ Jésù yóò ṣí ilẹ̀kùn alàjá fún mi, ní orúkọ Jésù.
23. Mo sọtẹ́lẹ̀ pé agbárakágbára tó bá fẹ́ fi mí rúbọ yóò pa ara wọn run lónìí, ní orúkọ Jésù.

24. Mo sọtẹ́lẹ̀ pé gbogbo agbára tó fẹ́ kí n sọkún yóò di gbígbé sin in níyìn lónìí, ní orúkọ Jésù.
25. Mo sọtẹ́lẹ̀ pe gbogbo ọfà tí wọ́n rán láti ṣí mi sílẹ̀ fún ìgbóguntì yóò padà sọ́dọ̀ àwọn tó rán an, ní orúkọ Jésù.
26. Olúwa yóò jẹ́ kí àkokò yìí jẹ́ àkokò ìdáhùn àwọn àdúrà mi, ní orúkọ Jésù.
27. Olúwa yóò jẹ́ kí ètò àwọn ọ̀tá mi  gbé wọn mìn, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo àtakò búburú, tí wọ́n gbé dìde láti dènà òmìnira àti dídi nlá mi yóò gba iná, yóò sì túká, ní orúkọ Jésù.
29. Olúwa Ọlọ́run àwọn ọmọ-ogun yóò parẹ́ ohunkóhun tó n fa ìkórìra, àìlójúrere àti ìjákulẹ̀ mọ́ra nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
30. Olúwa yóò fọ́ gbogbo ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀ òkùnkùn tó n jẹ́ kí àwọn ohunrere jìnà sími, ní orúkọ Jésù.